EFF'S SURVEILLANCE SELF-DEFENSE

# BÍ A ṢE LÈ: F'ÀÀYÈGBA ÌFẸ̀RÍLÀDÍ ỌLỌ́NÀ-MÉJÌ

*https://ssd.eff.org/en/about-surveillance-self-defense*

LOCALIZATION LAB

# Bí a ṣe lè: f'ààyègba ìfẹ̀ríláḍí Ọlọ́nà-méjì

Ìtúnwò Ìkẹyìn:
9-7-2017

Ìfẹ̀rílàdí ọlọ́nà-méjì (tàbí 2FA) ni ìgbésẹ̀ ìdánimọ̀ òǹlò nípa lílo àkójọpọ̀ ìfẹ̀rílàdí oríṣi méjì láti lo iṣẹ́ apèsè. Èyí lè jẹ́ ohun tí òǹlò mọ̀ (bíi ọ̀rọ̀-ìfiwọlé tàbí PIN), ohun tí òǹlò ní (bíi àmì iṣẹ́-àrídìmú tàbí ẹ̀rọ-ìbánisọ̀rọ̀), tàbí nǹkan tí a fimọ́ tàbí tí kò ṣe é yà s'ọ́tọ̀ lára òǹlò (bíi ìtẹ̀ka wọn).

O ó ti máa lo 2FA nínú ìgbé ayéè rẹ. Bí o bá lo ATM láti gbowójádé, o gbọdọ̀ ní ike pélébé ilé-ìfowópamọ́ọ̀ rẹ (ohun tí o ní) àti PIN rẹ (ohun tí o mọ̀). Ní báyìí, ọ̀pọ̀ iṣẹ́ orí ayélujára á máa lo ìdánimọ̀ kan ṣoṣo fún òǹlò wọn gẹ́gẹ́ bíi ààtòàbáwá - ọ̀rọ̀-ìfiwọlé.

## Báwo ni 2FA ṣe ń ṣiṣẹ́ lórí ayélujára?

Àìmọye iṣẹ́ orí ayélujára - títí kan Facebook, Google, àti Twitter - ń pèsèe 2FA gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà mìíràn fún ìfẹ̀rílàdí ọ̀rọ̀-ìfiwọlé nìkan.. Bí o bá f'ààyègba iṣẹ́ yìí, wà á fi ọ̀rọ̀-ìfiwọlé àti ọ̀nà mìíràn ṣe ìfẹ̀rílàdí. Ọ̀nà kejì ni ọ̀kan nínúu SMS tàbí odù àlòlẹ́ẹ̀kan tí áàpù ẹ̀rọ alágbèéká afohunìkọ̀kọ̀ pamọ́ gẹ́gẹ́ bíi Afẹ̀rílàdí Google, Duo Mobile, áàpù Facebook, tàbí Clef) tí a yà s'ọ́tọ̀ fún iṣẹ́ yìí yóò gbà jáde.

Èyíkéyìí, ọ̀nà kejì ni ẹ̀rọ-ìbánisọ̀rọ̀ alágbèékáà rẹ, ohun tí ó sábà máa ń ní. Ibùdó-ìtàkùn-àgbáyé (títí kan Google) náà nítìlẹ́yìn ìpamọ́ odù alálòlẹ́ẹ̀kan, tí ẹ̀da rẹ̀ ṣe é gbà sórí ẹ̀rọ̀ rẹ, ṣe é tẹ̀ sórí ìwé, àti fi pamọ́ sí ibìkan. Ní kété tí o bá ti f'ọwọ́ sí i láti máa lo 2FA, o nílò ọ̀rọ̀-ìfiwọléè rẹ àti odù alálòlẹ́ẹ̀kan láti orí ẹ̀rọ-ìbánisọ̀rọ̀ alágbèékáà rẹ kí o tó ó r'áàyè wọ ìṣàmúlòo rẹ.

## Kí ló dé tí mo fi gbọdọ̀ f'ààyègba 2FA?

2FA ń fún ìṣàmúlòo rẹ ní ààbò tó péye nípa mímú ọ fi ẹ̀rí làdí ìdánimọ̀ọ rẹ ju ọ̀nà kan lọ. Èyí túmọ̀ sí wípé, bí ẹnikẹ́ni bá ti ẹ̀ gba ọ̀rọ̀-ìfiwọléè rẹ mú nípò kìnínní, wọn kò ní le è r'ọ́nà wọ ìṣàmúlòo rẹ àyàfi bí wọ́n bá ní ẹ̀rọ-ìbánisọ̀rọ̀ alágbèékáà rẹ tàbí r'ọ́nà ipò-kejì lo ìfẹ̀rílàdí mìíràn.

## Ǹjẹ́ 2FA ní àléébù?

Bótilẹ̀jẹ́pé 2FA ń fún ni ní ààbò tó péye fún ìfẹ̀rílàdí, ewu àtìmóde ìṣàmúlòo rẹ le è wáyé, fún àpẹẹrẹ, o kò mọ ibi tí o ṣ'ọwọ́ọ̀ ẹ̀rọ-ìbánisọ̀rọ̀ rẹ sí tàbí o ti pàdánùu rẹ, tàbí pààrọ̀ ike pélébé SIM rẹ, tàbí rìnrìn àjò sí ìlú mìíràn láì tan ìrìn-káàkiri orí ẹ̀rọ̀ rẹ.

Ọ̀pọ̀ nínú iṣẹ́ 2FA ní ń pèsè àkàsílẹ̀ "àpamọ́" kúkúrú alálòlẹ́ẹ̀kan tàbí odù "ìgbàpadà". Ẹ̀rìnkan o lè lo ọ̀kọ̀ọ̀kan odù yìí fi wọ ìṣàmúlòo rẹ, kò sì wúlò mọ́ lẹ́yìnwá.
Bí ọ̀kan-àn rẹ kò bá balẹ̀ nípa ìpàdánù ẹ̀rọ-ìbánisọ̀rọ̀ rẹ tàbí ẹ̀rọ ìfẹ̀rílàdí mìíràn, tẹ odù wọ̀nyí jáde kí o sì máa gbé e kiri.

Wọn yóò ṣì ṣiṣẹ́ bí "ohun tí o ní," níwọ̀n ìgbà tí o bá tẹ ẹ̀dà kan ṣoṣo, kí o sì tọ́júu odù náà kí o rí i dájú wípé ẹlòmíràn kò rí i tàbí r'áàyè sí i nígbàkúùgbà. Bí o bá lo odù àkópamọ́ tàbí pàdánùu rẹ, o lè gba òmíràn jáde tí o bá r'áàyè wọ inú ìṣàmúlò rẹ.

Ìṣòro mìíràn tí ẹ̀rọ 2FA tó ń lo iṣẹ́-ìjẹ́ SMS ni wípé iṣẹ́-ìjẹ́ SMS kò l'áàbò tó. Ó ṣe é ṣe fún ògbólógbòó adojúkọni láti r'áàyè wọ inúu ìṣàsopọ̀ ẹ̀rọ-ìbánisọ̀rọ̀ rẹ (gẹ́gẹ́ bíi àjọ aṣèwádìí ọ̀daràn tàbí ẹgbẹ́ arúfin kan) láti jí àti lo odù tí a lo SMS fi ránṣẹ́ sí ọ. Pàápàá adojúkọni tí kì í ṣe ògbólógbòó ti dáríi iṣẹ́-ìjẹ́ ẹlòmíràn sórí ilàa tirẹ̀, tàbí r'ọ́nà wọ ilé-iṣẹ́ apèsè àfihàn iṣẹ́-ìjẹ́ tí a fi ránṣẹ́ sórí ilà hàn láì nílò ẹ̀rọ-ìbánisọ̀rọ̀.

Bí ọkàn-an rẹ̀ ò bá balẹ̀ nípa ìdojúkọ, pa ìfẹ̀rílàdí SMS, kí o sì lo áàpù afẹ̀rílàdí bíi Google Authenticator tàbí Authy. Láìbọ́sírere, àṣàyàn yìí kò sí lárọ̀ọ́wọ́tó fún gbogbo iṣẹ́ afàáyègbà 2FA.

Nírọ̀pọ̀, lílo 2FA túmọ̀ sí wípé o lè máa gbé ìwífún tó pọ̀ ṣọwọ́ iṣẹ́ tí ò rọ̀ ọ́ lọ́rùn. Bí o bá ń lo Twitter, tí o sì lo orúkọ ìnagijẹ nígbà tí o forúkọsílẹ̀. Papàá bí o kò bá fi ìdánimọ̀ lẹ́kùnún rẹ̀rẹ̀ fún Twitter, àti bí o bá wọ̀ ọ́ lóríi Tor tàbí VPN, bí o bá f'ààyègba 2FA SMS, Twitter kò ní ṣaláì ní àkọsílẹ̀ ilà ẹ̀rọ-ìbánisọ̀rọ̀ alágbèékáà rẹ. Èyí ni pé, bí ilé ẹjọ́ bá pa á láṣẹ, Twitter lè fi ilà ẹ̀rọ-ìbánisọ̀rọ̀ rẹ dá ọ mọ̀.
Èyí lè máà jẹ́ ìṣòro fún ọ, ìyẹn bí o bá lo orúkọ àbísọ̀ rẹ lórí iṣẹ́kíṣẹ́, àmọ́ bí pípa ìdánimọ̀ọ rẹ mọ́ bá pọn dandan, ṣe àtúnrò nípa lílo 2FA SMS.

Níparí, ìwádìí ti fi hàn wípé àwọn òǹlò kan máa ń yan ọ̀rọ̀-ìfiwọlé tí kò nípọn tó bí wọ́n bá f'ààyègba 2FA tán, pẹ̀lú èrò wípé ọ̀nà kejì yóò dáàbò bò wọ́n. Rí i dájú wípé o yan ọ̀rọ̀-ìfiwọlé tí ó lágbára lẹ́yìn tí o bá ti f'ààyègba 2FA. Wo ìtọ́nà bí a ṣe ń ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀-ìfiwọlée wa fún olobó.

## Báwo ni mo ṣe lè f'ààyègba 2FA?

Èyí yàtọ̀ láti agbègbè s'ágbègbè, bẹ́ẹ̀ náà ni ìpèlórúkọ wọ́n yàtọ̀. Ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àkàsílẹ̀ àwọn ibùdó tó l'átìlẹ́yìn fún 2FA wà ní https://twofactorauth.org/. Fún àwọn iṣẹ́ tó wọ́pọ̀, o lè wo Ìtẹ̀jáde 2FA Ọlọ́jọ́ Méjìláa wa, tó ṣàpèjúwe bí o ṣe lè f'ààyègba 2FA lóríi Amazon, Ilé-Ìfowópamọ́ America, Dropbox, Facebook, Gmail ati Google, LinkedIn, Outlook.com àti Microsoft, PayPal, Slack, Twitter, àti Yahoo Mail.

Bí o bá fẹ́ ààbò tó pójú òṣùwọ̀n tí kò ní í jẹ́ kí olè lè jí ọ̀rọ̀-ìfiwọléè rẹ, ka àkàsílẹ̀ yìí kí o sì tan 2FA sílẹ̀ fún gbogbo ìṣàmúlò ibùdó-ìtàkùn-àgbáyé tí o ṣe kókó tí o gbẹ́kẹ̀lé.